To Clear

Pillows & Matresses
at Lower Prices
APPLY :–
**Y. T. Dosunmu**
27, JOHN STREET
LAGOS

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

## Akiyesi Pataki

A fi iwe yi se ikede si awon Asoju iwe Iroyin Eleti-Ofe ka kiri agbaiye wipe, enikeni ti ko ba fi owo ti o ti je ranse si wa ,ao pe le'o, ako si ni fi iwe irohin ranse si en be mo.

VOL. XI No. 608. LAGOS. SATURDAY, JANUARY 24 – JAN. 30, 1959 KOBO MEJI (2d).

# Gabriel Laja Pada Lo Gbewa Odun Meta Lehin Ejo Arotunro

EKO. Awon gbajumo enia meji, Ogbeni Gabriel Laja ti o ti tse oga Asanwo ni ogba Reluwe ri ati ogbeni Abudu Rahimi Ligali ni awon odaran meji ti nwon lo lu Oloye M. A. Okupe eniti a mo ni Olotu Bank (ile ifowopamosi) ti o nje Agbonmagbe Bank, ni ako lihin wipe Onisowo igi Gedu ni awon nse, nwon fi eton gba owo girimoyan lowo re bi oke meji-le ni-egbaa Poun.

A pe oro na ni owe, o ni aro ninu; laifa gun, oro na di ti olopa nwon si mu awon odaran mejeji de iwaju Adajo, Adajo na si la Gabriel Laja mo ewon odun meta ati Ligali mo ewon odun marun.

Laja ati Ligali so wipe, ejo ti nwon da fun awon ko te won lorun, nitorina nwon gbe ejo na lo si kotu Kotemilorun. Nwon fi egberun Poun se oniduro fun Laja, sugbon nwon ko gba iduro fun Ligali.

Adajo meta lo da ejo na ni kotu Kotemilorun, adajo agba Sir Adetokunbo Ademola lo se idajo na, o wipe, o ya on lenu lati gbo wipe nwon gba iduro fun Laja. lehin ti idajo ti gori re, o so pe, Kotu giga ko ni agbara lati gba iduro fun odaran be ayafi Kotu nla lo le se be, bi o ba ri eri pataki mu wa.

Nitorina, ki Gabriel Oluwole Laja lo bere si gbewa tire lati oni yi lo fun odun meta. Abo re o, enyin omo rotika - tika, omo aiye.

igbimo papo lati pa Dr Azikiwe patapata, oro na ko nse oja on nikan ore on kan ti o nje George Umeaku wa nibe pelu sugbon ore on na ti ku nisisiyi ore kan eniti o so pe oro na soju on ni Orijiaku.

Nwon bere lowo re pe bawo ni iku se tase pa enikeji re be O dahun pe Niger City Hotel awon enia kan yi pelu wa ka won mole nwon ko ri ona gba ni nwon ba be sile lati oju ferese.

(Wo yoku lori iwe kejo)

## Ejo Omoba Ifemenam Ni Kotu Azize

Li akoko ti nse ejo yi lowo ni irohin tun kan kakiri wipe okunrin miran tun bura nilu Onitsha wipe, on ri, on gbo on si wa nibe nigbati nwon se

LAGOS RACE CLUB

**Spring Meeting 1959.**

**Saturdays 14th, 21st & 28th February, 1959**

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P. O. Box, 51 Lagos or at the Race Course.

NOTE.- No Entry Fees will be refunded after the draw has been made. Entries close at noon on Tuesday 27th January, 1959.

Public Notice

# Electricity Corporation Of Nigeria

EXCHANGE OF LOCATION OF HEADQUARTERS AND LAGOS UNDERTAKING OFFICES

The locations of the Electricity Corporation Headquarters at Ijora and of the Lagos Electricity Undertaking at 13 Broad Street are to be interchanged during the course of the week commencing 26th January, 1959, and the transfer will be finally completed by 31st January, 1959.

There will be no change in the telephone numbers of the respective departments and sections of the Corporation.

With effect from the 2nd February the following changes in postal addresses will be operative:-

(a) Electricity Corporation of Nigeria Headquarters,
Private Mail Bag No. 2030,
Broad Street, Lagos.

b) Lagos Electricity Undertaking & District Office,
Private Maill Bag No. 1091,
Ebute-Metta,
Lagos.

Consumers' enquiries regarding Electricity bills and other related matters will continue to be received at 13 Broad Street until 30th January, 1959, after which they will be received at the Lagos Electricity Undertaking, Ijora.

No change will be made in the arrangements for payment of accounts at the recently established Cash Office at 133A Broad Street payments of accounts may also be effected at Ijora with effect from 2nd February, 1959.

**ARTHUR FAUL**
SECRETARY TO THE CORPORATION
23rd January, 1959.

# Itan Ajapa Ati Ekun

## Apa XI

Nibi aisan oku baba oba, Ajapa fi iya pupo je Ekun eyiti o fi oju han u gadagba, ti Ekun ko si gbodo fohun. Iya na si je Ekun ni ajegbe. Ijapa ni ipo ti o ga ju ti Ekun lo. Balogun ni Ekun je, sugbon Ajiroba ati Balogun ni Ajapa je fun oba.

Lojo kan, oba sun, o lala ri baba re. Baba na wi fun omo re oba wipe ki o lo wa ehin Erin 'meji ki o fi se oso sinu afin re ki odun to yipo bi beko, nigbati o ba di ni opin odun, oba yio ku.

Nigbati Ie mo oba bere si ronu pe kini on yio ti se. Ajapa ba oba damoran wipe ki o gbe agogo si ode, oba gbo o si gbe agogo na jade wipe enikeni ti o ba mu ehin Erin wa fun oba yio gba idaji dukia oba. Nigbati Ajapa gbo nipa eyi, o mura, o di igbo erin.

Bi o ti de o ri Erin anikan ti o dubule Ajapa lo si iwaju re, o wipe kongbon, kongbon. Erin wo o titi, o rerin, ... lori kini o nse lori le lori nisisiyi, ko sa tile ye mi. Ajapa dahun pe ... mi ndun, mo si ... agbara ti Orisa fun ... ko da, bi iwo Erin ti ..., mo le wo o ju ... sinu odo. Erin dide kiakia, o ki ara re lo sa, sa, ... o wipe, iru iwo Ajapa yi ewe? Bi mo tile wa lori aisan fun odun meta, iwo ha le da iru ... mi gbe nile ambosibosi ki iwo wa wo mi ludo? Ki Orisa Ogiyan mase jeki a ri ... ninu ....

Ajapa ... ori re gbona O wi fun Erin ... n iba eyi ti o wi ni ... mu okun wa ... ni ile on, on yio ... pada bo larin iseju marun ... ki Erin duro de on. Ajapa rin seku-seku o bu omi si ori, o si bere gbe okun ti o mu dani wa lati ile ko ju iseju meta lo Ajapa yo, o si nlaagun.

O fi okun si Erin lorun' o womi to Erin'mi lo, o ni bi o ti toyi on yio woo gunke. La'a oro gun o tun fi okun si Erinmi orun ni Erinmi ati Erinoke ba gbija. Bi Erinmi ba fa Erin loke ti o si nfe tese bo omi, Erin Oke yio wipe emi ni a lu Ajapa ewe kan emi Ajapa ku Abiru-bamba, lo tan mi randi. Bi o ba si tun di wipe ki Erinmi foju kan oke, yio wipe ha Emi pelu Ajapa kini ki a ti gbo emi Erin-mado, yio tun randi mole. Bayi ni Erin Oke ati Erin odo fa ara won ni afagba ti o fi re totun-tosi, nwon subu lule.

Ajapa wa dide o wa yo obe oleju meji o si fi pa Erin oke, o yo ehin re mejeji o kori si ilu. Bi o ti ng a ode Ekun koja lo Ekun ri o pe e o ya lo ba ekun. E ma ka iwe irohin Eleti-Ofe Lose ti o mbo ti e o gbo iru babanla jamba ti Ekun se fun Ajapa.

(Koiti pari)

# Ole Toji Aguntan Gbe Farakorin.

Okunrin kan ti oruko re nje Subairu Obanimo ti o ngbe Abule Ogboke Igba Okene, l'agbegbe ilu Kabba, ni o lo ji eran aguntan kan gbe, ti o si di sinu apo, ni 'jagun ba gberu lowuro ojo kan, nigbati Olopa sewo, oju eru ori re sile, o fese fe. Nwon le titi ki nwon to le ri mu ninu baluwe ile to lo sapamo si. Adajo kotu bu Ogorun poun fun ni sisan tabi ewon osu mefa fun Agutan bi oni poun meji-abo to jigbe.

Eyi mu wa ranti oku iya Afose lori okunrin Egun kan to lo ji elede gbe, ti o si pa elede na, o wa ko sinu Posi oku o gberu? nigbati o de enu bode ni Agbamda ti nwon bi lere wipe kini wa ninu posi ti o gberu? okunrin Egun na dahun pe oku iya Afose lowa nibe. Awon Onibode 'aku wipe ayafi ti o ba si posi na ki awon ri oku iya Afose to wa nibe ki o to koja.

Nigbana ni okunrin Egun ole na so wipe iya Afose le pupo alagbara obinrin si ni, bi e ba siwo, o le di oku elede nitoripe agbara re po. Ki a ma fa oro gun mo, nwon si posi na, oku elede ti jagunna jigbe ni nwon ba ninu re. Eo r'aiye bayi ?.

# Oko Ofurufu Rotodyne





Oko 'ofurufu ti a nwo aworan re yi Oga'ko Ogbeni Ronald Geliatly ti a nwo aworan re lapa otun yi wa ti o rin ibuso to din die ni igba fun wakati kan Eyi je akoko ninu oko ofurufu to rin irufe opolopo ibuso be larin wakati kan.

Oko ofurufu na gba to enia meji-din-ladota tabi eru bi tonnu merin-abo fun irinwo ibuso, bi o ti tobi to o si gbaye to.

## Oso Kan Nka Nile Adura Serafu

O bęrę ninu iwe wa osę tokoja

Awọn Aladura wa nlu ilu wọn kikan - kikan bi ęnipe nwọn ri mi, nwọn nho, nwọn nyọ, nwọn si npatęwọ bi ęnipe nwọn nwo mi.

Nigbogbo akoko yi mo njijadu ki nle bọ lọwọ awọn Ikoko na ti gbogbo wọn gunyę bi oromọ adię. Larin meji ija yi gbogbo egbogi mi ko si eyiti o ję, mobęrę si kigbe, sibę yala nwọn gbọ nwọn ko fę dahun ni, tabi nwọn ko gbọ nko tilę le sọ, nitori ariwo na pọ.

Ṣamọ - ṣamọ, lilọ ti awọn aję lọ si ọna Ikorodu nṣe ni wọn lọ mura ija wa, nwọn to iwọn ọgọjọ obinrin ti awọn ti apola igi lọwọ.

Ohun ti o yanilęnu ni pe, dide ti awọn aję de awọn Aladura tun yi orin wọn pada, nwipe awọn "Aję ba lęję, Odumare tun lę ṣe o" loju kanna awọn ọmọde kekeke ti o ti mba mi ja di omiran ọkunrin.

Ija ti a wi yi lo pa Ṣalewa iya ęlęja ni abule Iwọran, on lo pa Siyę ni Iwaiya, on lo pa Ọmọle ęgbę mi kan ni Majidun.

Nigbati mo ri aye bọ ni mo ba sa pada sile, awọn aję gbogbo ti salọ. Bi mo ti wọle, bęni awọn ọmọde kekeke na tun wọle tọ mi ti nwọn tun bęrę si mi lu.

Mo ke, ke, ke, nko ri ęnikan gba mi, nigbati o ṣe ni mo ri ọkunrin kan to daṣọ bora bi awọn oloye Eko, o ni rungbọn, o juwọ si awọn ọmọde na, o wa bere lọwọ mi pe, Kini mo fi ṣe ọ ti o nse nu nibini si mi? ngo fi han ọ loni pe gbogbo agbara ti o ni ję ofifo, bi iwọ ko ba gba temi, kiku ni iwọ yio ku.

Aiya mi ja mo bere pe kini ki nse? O ni ki nlọ si ile adura yẹn ni ọla ki nsi rohin gbogbo ohun ti mo ri yi, ati iru enia ti emi na ję..

Lęhin to pari ọrọ rę bęni ọkunrin na fo soke, o wipe nisisiyi ara rọ mi mo si gba ti Jesu. Bi ęnikan ba bere pe awọn egbogi rę da ? asi ko ado sigidi Akaraba, Arokundejo ati oriṣiriṣi bawọnni wa sita, gbogbo enia si ni nke Safula.

## Obinrin Kan Bi Omo Merin Lekan

IBADAN. Obinrin Ibo kan bi ọmọ merin ni ikunlę kan oruko omobinrin na ni Hannah Okodi ti o ngbe Race Course 'ni Ibadan meji ninu awọn ọmọ na ję okunrin, meji si ję Obinrin o bimọ na sinu ile Alaisan ti University College. Gbogbo awon ọmọ mererin ati iya wọn mbe ni alafia.



# ELETI - OFE

A-NJU-WON KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 608. SATURDAY JAN. 24 - JAN. 30, 1959


## Aja L'oni Eru ...

Iro ni pẹpẹ npa, ni ede orin awọn elegungun to wa si ... wa lati fi ba ẹnyin Ọkawe wa sọrọ lọsẹ yi, lori ipalẹmọ ti a nṣe lọtun-losi nisisiyi fun ti idibo yan awọn enia sinu igbimọ gbogbo-gbo ti a o ṣe ninu odun 1959 yi.

Ati bẹrẹ si kede wipe ki olukuluku mase jafara lati fi oruko silẹ nigbati asiko na ba to fun ti ọdọ wa nihin, gẹgẹbi ti ipinlẹ Ila-Orun ti nwọn ti bẹrẹ ti a si ngboro wipe nwọn nfi orukọ silẹ daradara. Eyi nikan ko to bi ki a tete ma gbiyanju lati ṣi arawa leti nipa ibo didi wa, papaa ni asiko yi ti o jẹ wipe awọn enia ti a ba dibo yan ni yio ṣe olutọkọ wa nigbati a ba gba Ominira, ki a le ronu wa jinlẹ lati mọ irufẹ ẹgbẹ ti o tọ, ti o si yẹ lati dibo fun nitoripe gbogbo awọn ẹgbẹ Oṣelu ni yio ma kede fun ibo wa, ṣugbọn a ni lati mo wipe : "Kosi igi meji obi ninu igbo, eyiti iba jọ bi obi ni o ya abidun," ko si ẹgbẹ kan ti o to duro ti, ti o to gbojule lẹhin ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group). Nitorina, ki olukuluku wa jẹki o joko sinu ọkan on wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ao dibo fun, ki igbadun ijoba Ominira le kari gbogbo wa.

Ẹ maṣe gbagbe o.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA o dara pupọ fun awon ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọ ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti won si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


No. 4

## THE NIGERIA POLICE

### Vacancies for Cadet Sub-Inspectors of Police

The next Basic Training Course is due to start at the Southern Police College, Ikeja, on 6th July 1959. Final Selection Boards for candidates for this Course will be held as follows :-

(a) FOR CANDIDATES OF NORTHERN ORIGIN RESIDING IN THE NORTHERN REGION

At the Headquarters of the Commissioner of Police, Northern Region, Kaduna, on 9th March, 1959.

(b) FOR ALL OTHER CANDIDATES

At the Headquarters of the Inspector-General of Police, Lagos, on 13th April, 1959.

Persons wishing to be considered for selection for the above mentioned Course who have not already submitted their application forms, should therefore do so without delay.

Application forms may be obtained at any Police Station in the country and instructions about the completion of these forms are printed upon them.

Full information regarding the qualifications required, terms or serviee and training, can be found in the Government Notice No 2382, Federal Gazette No. 81 of 4. 12. 58.

(T. W. JENKINS)
Ag Assistant Inspector General of Police
for Inspector-General of Police

## ABODE GOMINA LEBUTE APAPA



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn Minister ati awon Ọga pataki nibi iṣe ijoba ti nwon wa pade Gomina nigbati o pada ti ilu Oyinbo de.

## AWỌN HAUSA NGBARADI FUN ỌJỌ IṢAKOSO ARA ẸNI

KANO. A gbọ irohin wipe firi-firi ni awọn Hausa npalẹ mọ ọjọ isakoso ara ẹni (Self Govt) eyiti yio ṣẹlẹ ninu oṣu ti o mbọ, a si gbọ wipe ni ibi meji ni nwọn o ti ṣe awuye-wuye ọjọ iṣe akoso ara ẹni na, Ọkan nilu Kaduna, ati ekeji nigboro ilu Kano.

Latigbati odun yi ti bere, a gbo wipe ile ojo kan ko le mọ ki awọn ẹṣin bi mẹwa, tabi mẹjọ ma wọ igboro Kano wa. A gbọ pe ere nla ti nwon npe ni ere Durbar, ni nwon fẹ ṣe.

# Independence Commemorative Stamp Design Competition

The Federal Government of Nigeria proposes to issue a special set of four stamps to celebrate the independence of Nigeria which it is anticipated will be on the 1st October, 1960.

2. For this purpose it is proposed to hold a stamp design competition and members of the public are invited to submit designs.

3. The proposal is for four denominations, namely, 1d, 3d, 6d and 1/3d, each of a different design which must be indicative of the occasion. Where the motive of the design is not apparent a note should be added explaining the significance of the colours and symbols. The design should be suitable for reproduction by the Recess or Photogravure printing processes, and should omit the denomination of the stamp.

4. The stamps are to be size 38 m m by 25 m m in either horizontal or vertical format, and the drawings submitted should be of size "9 x 6". They should be completed in the colours proposed and in the form of 'finished roughs'.

5. The names of competitors should not be shown on the drawing but on a separate sheet attached to the drawing. The drawings should be enclosed in an inner sealed envelope which should be clearly marked "Nigeria Independence Stamp Competition" and should bear the competitors name and address on the reverse side of the envelope.

6. A prize of £100, together with a souvenir of the occasion, will be awarded for each designs accepted for inclusion in the series.

7. All designs submitted will remain the property of the Federal Government of Nigeria. The copyright in accepted designs will also become the property of of the Federal Government.

8. Adjudication of the designs submitted will be by the Independence Celebrations Committee, who will make its recommendations to the council of Ministers, whose decision will be final.

9. The inner sealed envelope referred to in paragraph 5 above, should be securely packed so as not to suffer damage in transit and contained in an outer sealed envelope, addressed to "The Controller of Posts, Posts and Telegraphs Headquarters, Lagos". The name and address of the sender should not appear on the outer envelope. The outer sealed envelope should be registered.

10. Entries should reach the above address not later than the 31st March 1959. Entries received after this date will not be eligible for the competition.

## Oloye Awolowo Lo Be Agbegbe Iwo-orun Wo



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Obafemi Awolowo on lo dide lo se abewo awon ilu to mbe l'agbegbe ijoba ipinle Iwo-Orun. O lo si Oyo o ba awon Gbagimole (Surveyor) nibi ti nwon gbe nko awon omoe akeko ni ise gbagimole. O ba Oloye A. O. Adeyi nibe ati oga agba nibise Gbagimole, Ogbeni J. Till.

Nigbati o kuro nibe, o tetare sibiti nwon nhun aso oti o si danrawo die, o si tun lo wo ibiti nwon ti nre owu aso laro. O si ba Ogbeni J.O Elumelu nibe.

## ZIK LO BE AGBEGBE ILA-ORUN WO



Eni ti a awo ninu aworan yi ni Dr Nnamdi Azikiwe, ti o nse asiwaju awon oselu ni agbegbe Ila-orun, o lo so asoye ohun ti nwon ba pada bo lati ilu oyinbo ti nwon lo.

## Ajomogbe Wo Ewon Odun Mewa

IBADAN Okunrin kan ti o nje Imoru Maradi ti o nse gegebi Alumongeri kakiri, ni a gbo wipe o lo ji omo ilewe kan gbe ni abule Olania ni Ikereku.

Ganiyu Kayode npada bowa sile lati ilewe, beni okunrin Imoru yi ki i mole, o si gbe le ejika, lo ba sare wo inu igbo lo.

Awon enia lepa Imoru ninu igbo na, nwon si ri mu. Okunrin na tojo niwaju adajo wipe iro ni nwon pa mo on, nitori pe, on je Alumongeri

Adajo Taylor so wipe, bawo ni enyin se je alanimo Olorun lati maji omo olomo gbe, iru iwa yi ko dara o ye ki a fi opin si.

Olopa ran Adajo leti wipe, Imoru yi ni okunrin kan ti o so niwaju adajo (Taylor) wipe, nwon nfi ebi pa on ni ogba ewon. Ibe ni adajo ba se idajo pe ki ajomogbe na lo si ewon odun mewa

BOOK NOW
For your special Xmas Bread Cakes and Confectionery Goods
ODUS BAKERY
BAKERS AND COFECTIONERS.
Director:-
Hon. Solanke Onasanya.
M. H. A., F. Inst. B. B.,
Dip. Bakery
77, OJU - ELEGBA ROAD.
Suru Lere.

# "Itan Ode Elegbeje Ado"

ELEGBEJE-ADO DE ODO OBA

Lati Owo Y. ADE BURAIMO

Kabiyesi o, mo ti onise yin. Kabiyesi kabiyesi Oba Alaiyeluwa ka'de pe lori ki ki bata pe lese o, emi Ola ogun o.

Oba bere oro :- Elegbeje ado Aye o.

Ayeo, ayeo o asiroloran obun ti mope e si nipe iwo ni Ogbagba ti o gbagba to ngba ara adugbo ti o si ngba awon ara ilu ati eru ina re papa, gbawa lowo awon Olosa to de igboro yi. Oloran Oba.

Edumare yio si mu e lowo nmu ogun na, iwo yio si segun awon Olosa na, iwo yio si segun awon olosa na lagbara awon Baba nla wa tio te ilu yi do. Elegbeje ado si se ase.

Elegbeje ado fesi oro oba Kabiyeri alaiyeluwa eo ni te, tete ki te lawojo efo, eo ni te lowo awon ara ilu ati agbegbe re pu la, lagbara Edumare, la gbara Odu-ifa merindinlo gun tio koko de ori ile aiye, agbara awon Iya mi osoroga, emi yio segun won.

Aki mu oko d'oko kio mo sise afi ailera agbe (Farmer), efi ase leni lowo ni yeo efi oju sile kie woran.

Elegbeje ado kuro lodo oba. O fi ona ile re pon o nlo nigbati yio se, o na oju ri awon oro enia tio ri lekan, Okunrin alaso meta, ati Iya Onirungbon yewuyewu o nlo si ona ile re na, Nigbati yio se awon oro enia meji yi pe ni oruko ti o nje, o si da won lohun lesekanna, gegebi oruko re se awon agba pa owe kan bayi pe "Oruko iso omo lo mba omo rin" o de odo won awon enia oro yi bere si soro bayi pe gbogbo oro ti Oba so fun e fi o bo le gba pere opa pa e, otito ni aso fun e.

Elegbeje ado ni ha! enyin ni opa ki ise emi Elegbeje ado emase fi oju kekere wo lunu Baba obe ni ise, emi kukuru bi iku, eniti iku ran pani ete loni, abuku kan yin loni yi gbigbo ti awon oro enia gbo bayi nko ti won won ni bi arani Oro Ologun ba danwo yio dan tan, Elegbeje-ado lesi pe, Enyin tara enyin komo pe bi areni ti ni ogun lo, iku ejo leni, gbigbo ti won gbo eyi nia tubo bi won Okunrin alaso si bora sile lati ba Elegbeje-ado ja. Elegbeje ado papa Okunrin Ogun nla arare.

## Iwe Si Awon Omo Esa-Oke

Olotu,

Jowo gba mi laye die ninu iwe re Oloyin mona lati ba awon omo ibile Esa-Oke soro nipa ilosiwaju ilu na, ilu yi je okan ninu awon ilu ti o mbe lati aye Ilesan a ti ti tedo lopolopo odun siwaju o g u n Kiriji.

Emi ti mo mba nyin soro yi papaa je omo Esa-oke sugbon latigba ti a ti tedo nko ri ilosiwaju kan ti o se pataki beni aiye gbe, gbe, ni a wa yi, eniti ko ba si ba won g b e ehin kule oluware ni nwon o gbe ju si.

Lasiko kan, awon gbajumo omo ilu yi ti oju re la die ko ara won jo lati ma mojuto ohun ti o ba nlo nilu a t i idagba soke ilu kaka ki ilu na ni ilosiwaju nse lo tunbo nrehin.

Lekan si, mo tun fi iwe yi kesi awon omo Esa-oke ki nwon jiiri fun ilosiwaju ilu ti a bi wa si a tile gbo wipe laipe yi Ajele kekere wa be ilu na wo awon baba wa ye e si nwon si fi oro edun won si iwaju re. Ajele si fi owe yi dabun pe "Agbajo owo ni a fi so aiya. Ejeki a dide si nkan ile ibi wa.

Emi ni
TONA OMO ESA-OKE

Kere o !

Ati ni orisirisi o g u n German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road Lagos

# Awon Onirohin Ijoba



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon ti o lo ko ise onirohin ijoba nilu Oyinbo. Awon ni a nwo bi nwon ti nrekoja niwaju Afin Oba Gesi. Oruko won ni nwonyi: lati owo osi, Oliban O. M. Danan ara ile Nyasaland, F. O Okoroji ara Ila-Orun Nigeria B. S. K. Banya ara ile Saro, C. C. Lokko ara ile Ghana, T. A. Owobokun ara Iwo-orun Nigeria ati O. Ogunfuka ara Eko.




## Omo Ile Nigeria Nilu Oyinbo



Omode kekere, ọmọ ọdun mejọ ti a nwo ninu aworan yi ti oruko re [illegible] Martins lo [illegible] odun kan lo yẹ obinrin oyinbo [illegible] si ti o lẹ [illegible] kan ti nwọn ni ṣe iranlọwọ fun [illegible] British Empire Society.

Awọn ẹgbẹ yi lo tiraka, ti nwọn si ṣe [illegible] kini ohun ti o nsaba ma fọ enia [illegible], nwọn [illegible] rẹ nwọn si mọ.

## Ogbeni Morrison Si Ile Eko



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni ọgbẹni Herbert Morrison nigbati o lọ si ile ekọ giga kan nibiti a o gbe ma kọ awọn akẹkọ ni ọgbọn ori ati ọgbọn inu Ile ẹkọ na si gba to ẹgbaa ọmọ akeko, tokunrin tobinrin lo si nkewe nibe. iye owo ti nwọn fi pari ile-we na, ati awọn ohun elo inu rẹ jẹ £671,000.

Larin ọdun 1957, Iye awọn ilewe alakọbẹrẹ ti a kọ pari nilu Oyinbo jẹ 2,644, ilewe giga jẹ 1,136 iye awọn ọmọ ti nwọn o gba sibẹ lati kọ ni ekọ jẹ 2,052,000.

ILU OMOBA ... (O bere lati ewe kini)

se ... na.

Enikan on U... fi ara sese ... sibu... Oni... kan ... nwon ... Nwon ... Onitsha fun awọn. Lojo yi ni on rojo fun awọn Ọlọpa gẹgẹbi ọrọ na ti lọ.

Adajo Justice John Bennet so pe opuro ni omoba Nando nitorina ki o lo san igba Poun. Bi ko ba fi san ki o lo si ẹwọn oṣu mejila.

## Al... Kun-Bi-Oje...



Eniti a nwo ninu aworan oke yi ni Hogan "King" B... ... awọn ako... ni Ọgbẹni kan ti nwọn npe n D...wy ... ni ilu America, Los Angeles, wipe ... jija ... ni ipari osu February to mbo yi, nitori pe ... lati gba oye na lowo rẹ. ... so wipe on ko ni fi oye na silẹ titi ti ... N ... ibi on yio fi gba Ommira. Bẹ, ni ki o ri o.

# Egbe Ajisegiri

Ni ọdun 1948 ni awọn aghajọ ọmọ ilu Ogbomoṣọ ti da ẹgbẹ kan silẹ ti nwọn npe ni, Ọmọ Ogbomoṣọ Ajiṣegiri, nwọn da ẹgbẹ na silẹ fun ilọsiwaju ilu wọn nwọn si adawo jọ lati fi ran awọn ti o ba jafafa ninu ẹkọ lọ silu Oyinbo, Amẹrika ati ilu Jamani fun ẹkọ giga



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye N.D. Oyerinde ẹniti o ti gba o... ... Professor ninu ẹkọ iwe, on si ni Ọtun Ṣọhun, Ogbomoṣọ; on lo ṣeleri ni ọjọ kan ninu ... Rio fun awọn Ogbomọṣọ Ajiṣegiri wipe on yio fa ... iwe si ilewe giga nla-nla meji lati fun ẹmọ ilu yi ... (Ogbomoṣọ) ni ẹbun ẹkọ ọlọfẹ ninu ilewe kọkan a si gbọ wipe bẹni o se.

Ileri yi wu Ọgbẹni J.A. Oyelowo lori nigbana tobẹ ti o fi ṣeleri wipe, bi ileri ti Professor ba je otito on yio fun egbe yi ni owo ọkọ alọ ati abọ ọmọ akẹko kan lọ si Amẹrika Ọgbẹni E.P. Akinwale na tun ṣeleri owo oko omokan Yesufu Majolagbe na tun ṣeleri Poun mokanlelogun.

Nitorina enyin ọmo Ogbomoso e gbaju mo ẹko nyin nitori ẹnyin ni iyo aiye loni. Ninu nyin ni oba wa Dokita, Adajo Loya Engineer Scientist Teacher Printers Chemist Minister, Attorney ati bẹbẹ.


M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)



Inú dé, òkùnkùn paradà. M.B.T. de, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sáré. ... pòṣẹ̀ṣẹ̀. Àìá búburú wọ'gbó. ...èsún r'ẹhin-ẹ̀kùn. M.B.T. ...gùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'ikan, amú ni yàgbẹ́ bi òkùn, amú ni tọ̀ bi ...àrẹ. Abiwẹ́rẹ́ f'aboyún, agbẹ̀jẹ̀ di fawọn abiyamọ. Ahọ́n-dúdú, ẹ̀sẹ̀-wíwú ati àiyà-jíjá ko si ṣẹ́ni ti nia a. 4/6d pẹ̀lú 1/6d owó-ọkọ̀.

ARADAN STORES P.O. Box 2
EBUTE-METTA.


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street Lagos P. O. Box 467 Phone 23370